# MOSE BẸRẸ IṢẸ́ RẸ̀

## Ẹksodu 4:1-23, 27-31

## ẸKỌ 49 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Bi o ba kù ọgbọ́n fun ẹnikẹni, ki o bère lọwọ Ọlọrun" (Jakọbu 1:5).**

### A fun Mose ni Iṣiri

Nigba ti Mose da Oluwa lohun pe, "Emi niyi" kò mọ ẹrù nlá nlà ti Ọlọrun n fẹ gbe le oun ni ejika. O wi fun Ọlọrun pe awọn eniyan naa ki yoo gbagbọ́ pe Ọlọrun ni O rán oun. Ṣugbọn Ọlọrun maa n ṣe afiyesi awọn nnkan kékèké ni finni-finni; bi a ba si n fẹ pe ki O lò wá, Oun yoo mu eto Rẹ̀ ṣẹ ninu wa.

Ọlọrun fun Mose ni awọn ami kan lati fi gbé igbagbọ́ rẹ̀ ró. O wi fun un pe ki o ju ọpá ti o wa ni ọwọ rẹ si ilẹ. Bi o ti ṣe bẹẹ, o di ejò, eyi dẹru ba Mose, o si sá kuro lọdọ rẹ̀. Ṣugbọn Ọlọrun kò fẹ ki Mose bẹru ohunkohun, O si sọ fun un pe ki o mu ejò naa ni irù rẹ̀; nigba ti o ṣe bẹẹ o tun pada di ọpa lẹẹkan si i. Iṣẹ iyanu nla ni eyi, o si yẹ ki o fun Mose ni ikiya ti o n fẹ; ṣugbọn Ọlọrun tun fun un jù bẹẹ lọ.

Nigba ti Mose tẹ ọwọ́ rẹ bọ inu ẹwu rẹ ti o si tun fa a jade gẹgẹ bi aṣẹ ti Ọlọrun pa, "si kiyesi i, ọwọ rẹ dẹ́tẹ̀, o fún bi ẹ̀gbọ̀n owu." A ti kọ́ ẹ̀kọ́ tẹlẹ nipa bi ẹ̀tẹ̀ ti jẹ arun ti o buru lọpọlọpọ, ati gẹgẹ bi o ti jẹ arun ti kò ṣe e wò, afi bi Oluwa ba wò o san. Dajudaju o ni lati jẹ iyalẹnu fun Mose lati ri arun yii ni ọwọ́ rẹ̀, ṣugbọn Ọlọrun tun sọ fun un pe ki o tun fi ọwọ rẹ bọ àyà rẹ, nigba ti o si fa a jade, o si mọ́. Iṣẹ iyanu nla ni iwọnyi, Ọlọrun si ṣeleri pe Oun yoo tun ṣe e niwaju awọn Ọmọ Israẹli ati niwaju Farao, ki gbogbo wọn ba le gbagbọ́ pe Ọlọrun ti agbara Rẹ̀ pọ̀ ju ti ẹda lọ wà pẹlu Mose. Bi wọn kò ba gbagbọ́ sibẹ, ki Mose lọ bu omi ninu odò naa ki o si dà a silẹ, yoo si di ẹjẹ. Dajudaju kò si ẹni kan ti yoo ṣiyemeji mọ́ lẹyin gbogbo nnkan wọnyii.

### Igbọran ṣe Danindanin

Ṣugbọn Mose n tẹnu mọ ọ̀ran ailera rẹ sibẹ. O gba Ọlọrun gbọ́, ṣugbọn o dabi ẹni pe ko gbagbọ́ pe oun le ṣe iṣẹ ti Ọlọrun n fẹ ki o ṣe. O ṣe pataki pe ki a rẹ ara wa silẹ niwaju Oluwa; ṣugbọn o tun ṣe ohun pataki lati mura tan lati ṣe ohun ti Ọlọrun n fẹ ki a ṣe nigba ti a tilẹ rò pe a kò le ṣe e, bi a ba n fẹ lati wu U. A ni lati wà gẹgẹ bi amọ̀ ti o n fẹ ki amọkoko mọ oun si ọnakọna ti o ba n fẹ lati fi ṣe ohun-elo ti o wúlò.

A ti kọ́ ninu ẹ̀kọ́ wa pe nigba ti Jesu n pe awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ si ọdọ Rẹ̀, Oun kò pe awọn eniyan ti wọn ti di ọ̀jọ̀gbọ́n ninu imọ̀ Ofin, awọn ti wọn ni ipo ninu Tẹmpili, ṣugbọn O lọ si aarin awọn onirẹlẹ ti yoo le waasu Ọrọ naa ti O ba ran wọn.

### Apẹẹrẹ Ìgboyà

Nigba ti Dafidi jade lọ lati pa omiran nì, oun ko mu awọn ohun ija wọnni ti awọn jagun-jagun maa n lò, ṣugbọn awọn okuta ti o jọ̀lọ̀ ti o ṣà leti odo fun kannakanna ni ohun ija ti o tobi to lati bi ọ̀tá naa wó. Samsoni mú pari ẹ̀rẹ̀kẹ́ kẹtẹkẹtẹ kan o si lò ó fun ohun ija ti o fi pa ẹgbẹrun eniyan. Oun kò ṣe awawi pe iranlọwọ kò si fun oun nitori pe oun kò ni awọn ohun ija bi ibọn, ṣugbọn o lo ohun-elo ti o wà lọwọ rẹ, Ọlọrun si bukun un. Ọlọrun ki i beere lọwọ wa ju eyi ti a le ṣe lọ, ṣugbọn O n fẹ ki a lo ohunkohun ti O ba fi fun wa lati lo ni ọna ti yoo mu èrè ti o dara ju lọ jade. Ọlọrun le lo awọn ohun kékèké lati fi ṣe iṣẹ nla. Paulu kọwe bayii si awọn ara Kọrinti, "Ọlọrun ti yàn awọn ohun wère aiye lati fi dãmu awọn ọlọgbọ́n; Ọlọrun si ti yàn awọn ohun ailera aiye lati fi dãmu awọn ohun ti o li agbara" (1 Kọrinti 1:27).

### Ẹmi ni O N Jẹri

Mose rò pe oun ki i ṣe olóhùn iyọ̀, ati pe kò si ẹni ti yoo fẹ lati gbọ́ ọrọ oun. Ọlọrun maa n ro nipa ẹmi ti o wà ninu eniyan ju ọna ti o n gbà sọrọ lọ. A o tun tọka si ọ̀rọ̀ Paulu: "Bi mo tilẹ nfọ oniruru ede ati ti angẹli, ti emi kò si ni ifẹ, emi dabi idẹ ti ndún, tabi bi kimbali olohùn goro" (1 Kọrinti 13:1). Bi eniyan ba le maa sọ̀rọ̀ pẹlu ohùn iyọ̀ bi ti angẹli, ti kò si ni Ẹmi Ọlọrun pẹlu rẹ, ẹni naa n dún leti Ọlọrun bi koroba ofo ni.

Inu bi Ọlọrun si Mose nitori gbogbo awawi ti o n ṣe. Ki ha i ṣe Ọlọrun ni O da ẹnu Mose, Oun kò ha ni fi ọrọ ti yoo sọ si i lẹnu? Ṣugbọn Ọlọrun gbe ọrọ sisọ naa kuro lori Mose O si rán ẹgbọ́n rẹ Aarọni lati maa ṣe ẹnu fun un. Wọn yoo jijọ maa ṣiṣẹ papọ, Aarọni yoo jẹ ẹnu fun Mose, Mose yoo si maa sọ gbogbo ọrọ ti Ọlọrun ba sọ fun un fun Aarọni.

Lai si aniani, Mose kò ti i ri arakunrin rẹ̀ lati igba ti o ti fi Egipti silẹ niwọn ogoji ọdun sẹyin, ṣugbọn Ọlọrun wi pe Aarọni n bọ wa pade rẹ. Mose dagbere fun baba iyawo rẹ, o mu awọn ẹbi rẹ o si bẹrẹ irin-ajo rẹ pada si Egipti. Nigba ti o pade Aarọni wọn fi tayọ-tayọ ki ara wọn, Mose si sọ gbogbo nnkan ti Ọlọrun ti fi hàn an fun un.

### Ọlọrun Lo o

Lẹyin ti Mose ati Aarọni de si Goṣeni, Aarọni sọ gbogbo nnkan wọnni ti Ọlọrun ti sọ fun Mose fun awọn Ọmọ Israẹli; wọn si ṣe iṣẹ-iyanu sisọ ọpa di ejò, ati ti ọwọ Mose ti o dẹ́tẹ̀, niwaju awọn agba eniyan naa, wọn si gbagbọ́ pe Ọlọrun ni O rán wọn. Wọn tẹriba ni irẹlẹ lati sin Ọlọrun, pẹlu ọkàn ọpẹ, nigba ti wọn gbọ́ pe Ọlọrun n fiyesi ipọnju wọn ati pe yoo gba wọn kuro ni oko-ẹrú.

**AWỌN IBEERE**

1 Awọn awawi wo ni Mose n ṣe niwaju Oluwa nigba ti O pè e?

2 Njẹ Oluwa gba awọn awawi wọnyii?

3 Njẹ awọn eniyan naa gbagbọ́ nigba ti wọn ri awọn ami naa?

4 Nigba ti a ba n sọ ẹri wa ki ni ohun ti o ṣe pataki lọpọlọpọ ju ohun-iyọ̀ lọ?

5 Ki ni awọn ohun-ijà ti ẹmi ti Ọlọrun n fun awọn ọmọ Rẹ̀?